# IṢẸ́-ISIN AWỌN ỌMỌ LEFI

## Numeri 3:5-17, 21-45; 4:1-15, 24-33

## ẸKỌ 90 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ohunkohun ti ẹnyin ba nṣe, ẹ mã fi tọkàntọkàn ṣe e, gẹgẹ bi fun Oluwa, kì si iṣe fun eniyan" (Kolosse 3:23).**

**Iranwọ fun Awọn Alufaa**

Ọlọrun ti yan Aarọni ati awọn ọmọ rẹ̀ mẹrin lati jẹ́ alufaa, ati lati ṣe iṣẹ-isin fun Un ni Ibi Mimọ́ ninu Agọ́. Ṣugbọn meji ninu awọn ọmọ rẹ̀, Nadabu ati Abihu, ti kú niwaju Oluwa nitori wọn lo iná ajeji ninu iṣẹ-isin wọn. Aarọni, Eleasari ati Itamari ni wọn kù; ko si ṣe e ṣe fun awọn nikan lati ṣe gbogbo iṣẹ ti wọn ni lati ṣe nipa iṣe itọju Agọ ati rirú ọpọlọpọ ẹbọ wọnni, ki a má ṣẹṣẹ sọ nipa titú Agọ naa palẹ ati gbigbe e ró ni gbogbo akoko ti awọn Ọmọ Israẹli ba n lọ ni irin-ajo wọn. Gbogbo ohun ọṣọ́ mimọ́ -- Apoti Majẹmu ati awọn kerubu, pẹpẹ wura, ọpa fitila wura, tabili akara ifihan, pẹpẹ idẹ, ati agbada omi – ni a ni lati gbé pẹlu. Yoo gba ọpọlọpọ eniyan lati ru ẹru wuwo bayii. Bi o tilẹ jẹ pe wọn ni kẹkẹ ti yoo ru awọn apáko ti a fi wura bò, ati aṣọ ikele Agọ naa, o gba ọpọlọpọ eniyan lati fi pẹlẹpẹlẹ gbé gbogbo ohun ti a fi ṣe ibi mimọ́ yii.

Ọlọrun ri i pe awọn alufaa n fẹ iranwọ, nitori naa O fun wọn ni ẹya Lefi lati ṣe iṣẹ-isin yii. Ẹya yii ti fi ifẹ lati sin Ọlọrun hàn ni ọjọ ti Mose pe Israẹli nijà pe: "Tani wà niha ti OLUWA"? Awọn eniyan wọnyii ti dá ẹ̀ṣẹ nla nipa sisin ẹgbọrọ maluu wura, Ọlọrun si fẹ pa gbogbo awọn eniyan wọnyii run nitori wọn ti ṣe aigbọran si I. Ṣugbọn Mose gbadura kikankikan fun igba pipẹ́ fun wọn, Ọlọrun si dá wọn si. O hàn gbangba pe ẹya Lefi kò kó ipa ninu isin ẹgbọrọ maluu naa. Ọlọrun si yàn wọn lati ṣe iṣẹ pataki fun Oun ninu Agọ́.

**Ya Awọn Ọmọ Lefi Sọtọ**

Ọlọrun sọ fun Aarọni lati wẹ awọn ọmọ Lefi mọ́, ki o si rú awọn ẹbọ pataki lati yà wọn sọtọ fun iṣẹ isin. A fun wọn laṣẹ lati pagọ ti wọn yí Agọ Ajọ ká, nitosi ibi ti Ọlọrun wà. Wọn yoo jẹ́ oluṣọ, nitori bi alejo kan ba sunmọ itosi ju bi o ti yẹ lọ oun yoo kú. Ọlọrun fẹ ki a pa Ibi Mimọ́ Rẹ̀ mọ́ ni mimọ́.

Agọ yii wà ni aarin ibudo awọn Ọmọ Israẹli. Oun ni kókó ati olubori ti igbesi-ayé awọn Ọmọ Israẹli so mọ yika. Isin Ọlọrun gbọdọ jẹ ohun ti o ṣe pataki ju lọ fun wọn. Bakan naa ni o gbọdọ ri fun wa pẹlu. O ṣe danindanin fun wa lati ṣe iṣẹ ti Ọlọrun fun wa ju lati tẹ́ ara wa tabi awọn ọrẹ wa lọrun. Ọlọrun n fẹ ki a fẹran iṣẹ-isin Rẹ̀ pẹlu gbogbo ọkàn wa, bi a bá si ṣe bẹẹ, a o fẹ ṣe ifẹ Rẹ̀ nigba gbogbo. Ni owurọ, nigba ti a ba bẹrẹ ọjọ kan, a o gbadura si Jesu lati pa wa mọ la ọjọ naa já, ati lati ràn wa lọwọ ki a má ba ṣe ohunkohun ti Oun kò fẹ ki a ṣe. Bi ohun kan ti a kò ni ireti ba de ba wa lọjọ naa, a o beere lọwọ rẹ̀ bi o ba jẹ ifẹ Rẹ̀ fun wa lati ṣe e. Nigba ti alẹ ba lẹ́, a le dupẹ lọwọ Ọlọrun pe a ti gbé igbesi-ayé wa lati wu U.

**Ibugbe Ẹya Kọọkan**

Niha ila-oorun Agọ́, ni ẹnu ọna rẹ, ni awọn ẹya Judah, Issakari ati Sebuluni wà. A ti n reti ohun ti o ṣe pataki lati ọdọ ẹya Judah nitori Jakọbu ti sọtẹlẹ pe: "Judah, iwọ li ẹniti awọn awọn arakọnrin rẹ yio ma yìn; . . . . Ọpá-alade ki yio ti ọwọ́ Judah kuro, bẽli olofin ki yio kuro lãrin ẹsẹ̀ rẹ̀, titi Ṣiloh yio fi de; on li awọn enia yio gbọ́ tirẹ̀" (Gẹnẹsisi 49:8-10). Eyi ni asọtẹlẹ nipa Jesu ti yoo wa bi Messia lati inu ẹya Judah.

Niha guusu Agọ, ni awọn ẹya Reubẹni, Simeoni ati Gadi wà; niha iwọ-oorun ni awọn ẹya Efraimu, Manasse ati Bẹnjamini wà; niha ariwa si ni ẹya Dani, Aṣeri ati Naftali wà. Efraimu ati Manasse jẹ awọn ọmọ Josẹfu mejeeji, ati nitori ijolootọ Josẹfu ni Egipti, Ọlọrun ṣeleri ilọpo meji ogun fun un nigba ti awọn Ọmọ Israẹli ba de Kenaani. Efraimu ati Manasse yoo gbà ipin kọọkan gẹgẹ bi awọn arakunrin Josẹfu ti ṣe gbà.

Laaarin Agọ ati ibudo awọn Ọmọ Israẹli iyoku ni awọn ọmọ Lefi wà, pẹlu Aarọni ati awọn ọmọ rẹ̀ niwaju ẹnu ọna Agọ gan an. Awọn ọmọ Lefi jẹ iranṣẹ Ọlọrun pataki, wọn si n gbé nitosi Rẹ̀. Wọn wà ni imurasilẹ nigbakigba lati ṣe iṣẹ-iranṣẹ wọn nigba ti a ba n fẹ wọn. Awọn ti n sin Ọlọrun gan an ni awọn ti wọn sun mọ Ọn timọtimọ. Wọn wà nitosi lati gbọ́ nigba ti O ba n sọ ifẹ Rẹ̀ si wọn lohun jẹjẹ, wọn si ṣe tan lati gbọran.

**Ọlọrun Gba Awọn Akọbi**

Ni alẹ ọjọ ti Ọlọrun mu awọn Ọmọ Israẹli jade kuro ni Egipti, angẹli apanirun la ilẹ naa já, awọn akọbi ọmọ si kú ni ile kọọkan – ayafi ibi ti ẹjẹ ba wà lara ilẹkun. Ọlọrun ti fun awọn Ọmọ Israẹli ni ọna ati bọ́ lọwọ ikú naa. Bi wọn ba mu ọdọ-agutan kan, ti wọn pa a, ti wọn sun un, ti wọn jẹ ẹ, ti wọn mú ninu ẹjẹ rẹ̀, ti wọn si fi si ara opo ilẹkun ile wọn, angẹli apanirun yoo ré wọn kọja. Aanu Ọlọrun ni o dá ẹmi awọn akọbi ẹbi kọọkan si, O si wi pe lati ọjọ naa lọ, wọn jẹ ti Oun. "Nitoripe ti emi ni gbogbo akọ́bi ninu awọn ọmọ Israẹli, ati ti enia ati ti ẹran: li ọjọ́ ti mo kọlù gbogbo akọ́bi ni ilẹ Egipti ni mo ti yà wọn simimọ́ fun ara mi" (Numeri 8:17). Wọn yoo jẹ́ aṣoju awọn ẹbi wọn ninu iṣẹ-isin wọn ninu Agọ.

**Awọn Ọmọ Lefi Rọpo Awọn Akọbi**

Ṣugbọn lẹyin igba ti awọn Ọmọ Israẹli dẹṣẹ, Ọlọrun yan ẹya Lefi lati maa ṣe iṣẹ iranṣẹ fun Un dipo awọn akọbi ẹbi kọọkan. "Ati emi, kiyesi i, emi ti gbà awọn ọmọ Lefi kuro lãrin awọn ọmọ Israẹli ni ipò gbogbo akọ́bi" (Numeri 3:12). Ni ọpọlọpọ igba, nigba ti Ọlọrun ba n ba Mose sọrọ nipa gbigba awọn ọmọ Lefi fun ara Rẹ̀. O wi pe, "Emi ni OLUWA." O n fẹ ki awọn eniyan mọ pe Oun ni ẹtọ lati gba awọn eniyan wọnyii fun ara Rẹ̀. Oun ni Ọlọrun Ọrun ati ayé, Oun si ni aṣẹ lati yan ẹnikẹni ti o ba wu U si iṣẹ-isin Rẹ̀.

Awọn ọmọ Lefi kò gbọdọ ni ogún kan nigba ti wọn ba de ilẹ Kenaani, ayafi ilu ti wọn yoo gbé. Idamẹwaa ti awọn Ọmọ Israẹli iyoku ba mú wá ni yoo jẹ́ ti wọn. A fun wọn ni ilẹ ti o to fun maluu ati agutan wọn, eyi ti a yà sọtọ fun Ọlọrun pẹlu dipo akọ́bi agbo agutan ati maluu awọn Ọmọ Israẹli.

**Kika Awọn Akọbi**

Ẹya Lefi pin si ipa mẹta: Gerṣoni, Merari ati Kohati. Bi a ba ka iye ẹbi kọọkan, gbogbo wọn lapapọ jẹ ọọdunrun le ni ẹgbaa mọkanla (22,300); sibẹ ni ẹsẹ kọkandinlogoji (39) wọn jẹ ẹgbaa mọkanla (22,000). Ọọdunrun (300) ni iyatọ laaarin ọọdunrun le ni ẹgbaa mọkanla ati ẹgbaa mọkanla. Alaye iyatọ yii ni pe ọọdunrun awọn ọmọ Lefi jẹ akọbi ninu awọn ẹbi wọn pẹlu, awọn ti wọn i ba jẹ ti Ọlọrun bi o bá tilẹ ṣe pe a kò yan awọn ọmọ Lefi fun iṣẹ-isin agọ́. Nitori naa a kò le kà wọn si ẹni ti o gba ipo awọn akọbi ẹbi miran. Akọbi awọn Ọmọ Israẹli jẹ ẹgbaa mọkanla ati ọrinlenigba o din meje (22,273); awọn ọmọ Lefi si jẹ ẹgbaa mọkanla (22,000), nitori naa a gbọdọ rọpo ọrinlenigba o din meje (273), iyooku lọna miiran. Ọlọrun sọ fun Mose pe awọn eniyan le san iye owo kan sinu iṣura lati ra olukuluku ẹni ti Lefi kò rọpo pada. A ko mọ ẹni ti o san owo naa; boya a pin in laaarin gbogbo ijọ eniyan ni.

**Eto Irin-Ajo Wọn**

Ọlọrun n fẹ ri i pe a ṣe gbogbo nnkan letoleto ninu ile isin Rẹ̀. O sọ iru iṣẹ ti awọn ọmọ Lefi yoo ṣe fun wọn. Wọn yoo ma ran awọn alufaa lọwọ ninu iṣẹ-isin wọn ninu Agọ, wọn yoo si maa tọju gbogbo ohun ọ̀ṣọ́ inu rẹ̀. Nigba ti awọn Ọmọ Israẹli ba si ṣí, ẹbi kọọkan ni iṣẹ pataki lati ṣe ni titú Agọ palẹ ati lati gbe e ró ni ibi ti wọn yoo tun pagọ si.

Nigba ti aṣẹ ba wa pe ki wọn tẹ̀ siwaju, Aarọni ati awọn ọmọ rẹ̀ yoo lọ sinu Agọ, wọn yoo fi ibori ti a pese silẹ bo gbogbo pẹpẹ ati awọn ohun ọṣọ inu agọ, wọn yoo fi aṣọ ikele ti o gé Ibi Mimọ́ Julọ sọtọ, bo apoti ẹri, wọn yoo si fi ibori awọ seali bo o. Lẹyin naa wọn yoo bo awọn pẹpẹ, ọpa fitila, tabili akara ifihan, ati gbogbo awopọkọ, awo turari ati awọn ṣibi. Gbogbo nnkan yoo si wà ni imurasilẹ lati tẹ̀ siwaju ni irin-ajo wọn.

Nigba naa ni awọn ọmọ Kohati yoo wọ inu Agọ, wọn yoo si gbé gbogbo awọn ohun ọṣọ mimọ́ yii, olukuluku yoo gbé ẹru ti a yàn fun un, eyi ti yoo gbé le ejika rẹ̀. Awọn alufaa ni lati ṣọra gidigidi lati ri i pe a bo gbogbo nnkan, nitori bi awọn ọmọ Kohati ba fi ọwọ kan ohun ti a kò bò, wọn yoo kú. Eleasari, ọkan ninu awọn alufaa yoo fi pẹlẹpẹlẹ ṣe akiyesi pe a ṣe gbogbo nnkan letoleto, a si tọju rẹ̀ daradara.

Awọn ọmọ Gerṣoni ni o n ṣe itọju awọn aṣọ ikele ati isorò. Gẹrẹ ti awọn ọmọ Kohati ba ti gbé awọn ohun ọṣọ inu agọ jade, ni awọn ọmọ Gerṣoni yoo ti bẹrẹ si ká aṣọ ọgbọ ti a fi ṣe agbala ode ati eyi ti a fi ṣe ilẹkun. Wọn yoo kó awọn ibori ti a fi ṣe Agọ kuro: aṣọ ọgbọ wiwẹ ti a ṣe ọna si lara ti ó wà ninu, ibori ti a fi awọ ewurẹ ṣe, ibori awọ agbo ti a ṣe ni pupa, ati ti awọ seali. Itamari ni o maa n boju to iṣẹ́ yii, yoo si ri i pe tọwọtọwọ ni a fi gbé awọn aṣọ-tita naa.

Itamari pẹlu, maa n boju to iṣẹ titu awọn apako ti a fi ṣe Agọ́. Awọn ọmọ Merari ni a yàn si iṣẹ yii. Apako kọọkan ni a o fà jade kuro ninu ihò rẹ̀, olukuluku si mọ eyi ti oun ni lati gbé ninu Agọ mimọ́ Ọlọrun. Ẹru wọn wuwo, ṣugbọn bi ẹni kọọkan ba sa ipá ti rẹ̀, wọn o gbé Ile Ọlọrun yii siwaju pẹlu irọrun.

Awọn ọmọ Gerṣoni ati Merari wà lẹyin ẹya Juda, ti o ṣaaju awọn Ọmọ Israẹli ni irin-ajo wọn. Gẹrẹ ti Ọwọ̀n Awọsanma ti o n ṣaaju wọn ba ti duro, eyi ti o n fi han pe Ọlọrun fẹ ki awọn Ọmọ Israẹli pagọ, wọn yoo gbe apako Agọ duro lẹsẹ kan naa, wọn yoo si fi awọn ibori rẹ̀ bo o. Ni akoko ti awọn ọmọ Kohati, ti n tẹle ẹya kẹta, yoo fi dé, wọn yoo ti gbé Agọ yii duro, yoo si ku awọn ohun ọṣọ ti a n ko sinu rẹ̀.

**Ọlọrun ki i Ṣe Olupilẹṣẹ Ohun Rudurudu**

Ẹ jẹ ki a fi oju ẹmi wo rudurudu ti i ba wà ni ibudo awọn Ọmọ Israẹli nigba ti wọn n lọ ni irin-ajo wọn, bi wọn kò ba ni aṣẹ pataki nipa ibi ti wọn yoo pagọ si ati ibi ti wọn yoo lọ. Ọlọrun ti yan Mose ati Aarọni lati ṣiwaju awọn eniyan naa, wọn si gbodọ gbọran ninu ohun ti o le dabi ẹni pe o kere: ibi ti wọn yoo pagọ si, ati ibi ti wọn yoo lọ, ati akoko ti wọn yoo tẹ̀ siwaju ninu irin-ajo wọn. Ṣugbọn awọn nnkan "kékèké" wọnni ni o maa n mu ki ohun gbogbo lọ letoleto ninu ibudo Oluwa.

Ọlọrun pe awọn eniyan kan lati jẹ́ alufaa Rẹ̀, wọn si ni iṣẹ ti o lọ́wọ̀ lati ṣe fun Un. Nigba miiran awọn eniyan a ro pe awọn mọ bi a ti n ṣe nnkan ju awọn alufaa wọn, ṣugbọn inu Ọlọrun ko dun si iwa ijọra-ẹni-loju bayii. O n fẹ ki a ṣe isin Rẹ̀ ati iṣẹ Rẹ̀ letoleto, ẹnikẹni ti O ba si fi si iru ipo ifọkantan bayii ni yoo beere iṣiro lọwọ rẹ̀.

Ẹ jẹ ki a gbadura fun awọn alufaa wa ki a si ràn wọn lọwọ ninu iṣẹ-isin wọn fun Olugbala. Bi a ba jẹ́ oloootọ ninu ohun ti Ọlọrun fun wa lati ṣe, bi o tilẹ jẹ pe a le ro pe iṣẹ kékèké ni, Oun yoo fun wa lere ni ọjọ ti Onu yoo pín ère fun awọn ọmọ Rẹ̀.

**AWỌN IBEERE**

1. Ta ni awọn ọmọ Lefi?
2. Ki ni ṣe ti Ọlọrun yàn wọn fun iṣẹ isin agọ?
3. Ki ni ṣe ti Ọlọrun gba awọn akọbi fun ara Rẹ̀?
4. Darukọ ipa mẹta ti awọn ọmọ Lefi pín sí.
5. Ki ni iṣẹ ẹbi kọọkan?
6. Ipo wo ni awọn ọmọ Gerṣoni ati Merari wà ninu irin-ajo wọn?